**Owe**

Adie iba l'oko, iba l'atitan se nkan. Imado iba se bi elede a ba'lu ie, Eru iba j'oba, enia ko ba ti ku okan.


# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LEJỌ


**Asoje**

Enia ma jeki enia sunwọn, eni ma sunwọn ko ni gbọ. Apa ọmọde ko le ka igi Oṣe, o ma doyika.

VOL. X111 No 684. LAGOS. SATURDAY FEBRUARY 11, — FEBRUARY 17, 1961 KOBỌ MEJI (2D)

# NWON TU IGBIMO IBILE ILU ENUGU KA, AJABO KO SI FUN MAYOR!

ENUGU - Aragbabu irohin t i a gbọ niti abọ iwadi ẹsun owo biribiri ti nwọn fi igbimọ ibilẹ ilu Enugu sun, ti Ọgbẹni Perkins ṣe, ni o fa tituka igbimọ na wa.

Ẹsun owo pala-aia ati owo ahin gbigba ti nwọn fi igbimọ na sun ni Oluwadi so wipe ododo ni. Ọ ọ ajabọ ti wipe awọn Oselu kan l'odi rigimọ mọ wọn, ko mọyan lori, irọ patapata ni.

Oluwadi gba Alaṣẹ ijọba ibilẹ ni imọran wipe, ki o tu igbimọ na ka, ki o si wipe awọn Olugbimọ mọkan-dinlogun ti o ba Mayor ṣe iṣẹ buburu na pọ ko gbọdọ dibo fun ọdun marun.

Awọn niwọnyi :- Malam U m o r u A'tine, Mayor; Ọgbẹni Ezechi, Igbakeji, Mayor, Ọgbẹni Chikozi, Akuhue, Argu, Nwa u, Nwozuzu, Eze, Kene, Odiachi, Agu Nwoko, Udokwu, Agunwah, Odianye, Ogboz r, Ozonu Agwu ti J. M. Anyadiegwu.

Ati pe awọn Ogbakowe ilu Igbimọ bi: Akọwe ilu, Ọgbẹni J. N Emehe, Igbakeji akọwe ilu, Ọgbẹni E.C. Eboh, ati Ogbẹni Atunluṣe Town Engineer Ogbẹni P A. Nwankwo ti nwọn duro ti Olori Amofin ijọba yio fi yẹ ọrọ wọn wo, bi o ba'yẹ lati fi ofin gbe wọn. Eyiti o ba kan awọn Olugbimọ (Councillor) nibẹ, ki Olori Amofin yẹ wo lati ṣe eto fun wọn.

Alaṣẹ Ijọba ibilẹ ti gba bẹ. Awọn Alole enia marun ti nwọn yan si ile Igbimọ ibile na niwọnyi :- Ọgbẹni D. O. Nwosu, Alagba, Iyatin Okoye, Ọgbẹni A. N. Anagbu, Ọgbẹni J C Okeke ati Ọgbẹni N. C. Ọ b a. Awọn ni yio maa toju ilu ni asiko yi.

## Afape Joye Oluwa Rikisi Pin

EKO. Irohin ta siwa leti fenrẹn w i p e Ọgbẹni Abudu Rashidi Afape ti awọn ẹbi ile Oye Oluwa ti mu, ti o si ti wa ninu Iga ni iwadi ti nwọn ṣe fọre le lori.

Lehinti nwọn ti yan Afape sile, lati fi j'oye Oluwa ni awọn apakan ninu awọn ẹbi ile Oye Oluwa tako yiyan re ti ọrọ na di ohun ti ijọba ni lati lọwọ ninu re.

Nwọn yan awọn Oluwadi lati ṣe iwadi wo, ẹniti o tọ si lati jẹ Oye O l u w a ro'po Ologbe Alhaji Amodu Tijani, Oloye Oluwa ti o ṣalaisi. Nwon se iwadi na siwa-sẹ'hin, s'otun-s'osi, Ọgbẹni Abudu Raṣidi Afape kanna ni a gbo wipe ijoba f'aramo. Nwon yio de fila oye fun ni oju osẹ 12/2/61.

**Kuta-kuta pin, Afapẹ J'oye, abuṣe-buṣe.**

## Oba Obinrin Ati Oko Re Lo Be Iboji Mahatma Ghandi Wo



ỌBA Obinrin ilu Oyinbo, ọlọ'a Ọmọba Philip ni Ọba Obinrin nwọ bi o ti mbọ bata ẹsẹ rẹ lati wọ bata aboyọ nigbati nwọn fẹ lọ bẹ iboji Mahatma Ghandi wo ni Millea, Delhi Titun.

Ọba Obinrin pẹlu Ọkọ rẹ fi ododo oniyebiye le ori iboji na.

# BALE TITUN JE NI ILUGUN

ILUGUN -- Ọgbẹni S. O. Ṣogbẹin ti iṣe Alaṣẹ iṣẹ ijọba Iwọ-orun ni o sọ ni Orile-Ilugun ni agbegbe Ẹgba wipe ipo awọn Ijoye jẹ nkan pataki ni ilẹ omin ira Nigeria.

Alaṣẹ iṣẹ ijọba sọrọ yi nibi ayẹyẹ ifijoye Bale Orile-Ilugun ti nwọn fi Oloye M. O. Okunade jẹ Bale titun, o sọ wipe ijọba yio ṣe itọju oye yio si ma gbe ga ni ipinlẹ Iwọ-orun.

Ogbẹni Ṣogbẹhin sọ wipe oye titun na, Alake ati awọn ọba Ẹgba ati awọn Ijoye pẹlu gbogbo awọn Ẹgba ni o fọwọsi

Balẹ titun na jẹ ẹni ọgọta ọdun, on si ni o ti jẹ oye Balogun fun ọdun mẹwa. Awọn enia ti o pejupesẹ sibi ifijoye Balẹ na fẹrẹ to ẹgbata, pẹlu awọn Oloye ati awọn Olugbimọ lati Ẹgba Ọdẹda.


## OKU'JA WOLU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O NRA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO OTI SE LE RA OMIRAN. EYI NI GUN TI ONIṢOWO LE ṢE TI ỌJA RẸ YIO FI MA TA BI IṢU AKARA GBIGBONA

**E polowo O ja Yin**

**Sinu Iwe Irohin**

**ELETI-OFE**


# ABIYAMO SI OMO-OLOMO GBE NIILE ALABIYAMO

Freetown-- Nilu Saro ni a ti gbọ irohin kan wipe obinrin kan ti o lọ bimọ sinu ile Alabiyamọ, nigbati nwọn da silẹ wipe ki o maa lọ sile rẹ, ọmọ-ọlọmọ ni nwọn ṣi gbe fun u.

Nigbati iya ọmọ ti nwọn si gbe fun ẹlomiran lọ na mbere ọmọ tirẹ, ti nwọn si fi sẹ awatt ni nwọn to mọ wipe obinrin ti nwọn ti da silẹ ni o si ọmọ na gbe lọ, nitoripe nwọn ri ọmọ kan ti ko si iya rẹ ninu awọn alabiyamọ ti o wa ninu ile Alabiyamọ na

Lọgan ni nwọn fi moto ranṣe lọ si ile obinrin na lati lọ fi gbe t'on-t'ọmọ to gbe lọ sile wa, ki o wa gbe tirẹ ki nwọn le gbe ọmọ fun ọlọmọ.

Akiyesi d'ọwọ nyin, ẹnyin oṣiṣẹ ile Alabiyamọ.


Advt 20.

## Federation Of Nigeria Second Development Loan

The Central Bank of Nigeria have been authorised by the Federal Minister of Finance to raise in Nigeria a Federal Government loan of £10,000,000.

The Stocks to be issued will be :-

£2,000,000 5 o/o FEDERATION OF NIGERIA SECOND DEVELOPMENT STOCK 1967.
£4,000,000 5 1/2 o/o FEDERATION OF NIGERIA SECOND DEVELOPMENT STOCK 1977.
£4,000,000 6 o/o FEDERATION OF NIGERIA SECOND DEVELOPMENT STOCK 1985.

Interest, which will be paid half-yearly on the 22nd September and 22nd March, will accrue at the rates shown above and repayment will be made as follows :-

5 o/o Federation of Nigeria Second Development Stock, 1967 - on 22nd March, 1967.
5 1/2 o/o Federation of Nigeria Second Development Stock, 1977 - on 22nd March, 1977.
6 o/o Federation of Nigeria Second Development Stock, 1985 - on 22nd March, 1985.

Application lists for the loan will open on the 22nd FEBRUARY and close on 22nd MARCH, both dates inclusive. Applications must be in multiples of £10 and can be made only on the special forms avaliable at banks throughout the country. Application for different stocks must be made on the different application forms provided.

The stocks will be issued at par and payment in full must be made with applications ( i. e, £10 must be paid for every £10 of stock applied for ). Receipts will be issued for payments and will later be exchanged for Stock Certificates. If desired, payment may be made by means of a draft on a United Kingdom bank but payment in this way may be made only to the Central Bank of Nigeria direct, accompanied by the relative application form.

Notification of allotment will be made direct to subscribers by the Central Bank of Nigeria as soon as possible after the 22nd March and stockholders will be advised at the same time when to collect their Stock Certificates from the banks where they submitted their applications.

Pending the operation of a Stock Exchange in Lagos, prospective buyers and sellers of the stocks should, after allotment has been made, approach their own bankers who will get in touch with the Central Bank with a view to affecting a market.

Further information can be obtained from the Prospectuses available at banks on and after 22nd February.

**R. K. C. Giddings,**
GENERAL MANAGER.

Central Bank of Nigeria,
Tinubu Square,
Lagos.

February, 1961.



# E POLOWO OJA YIN SINU IWE IROHIN ELETI - OFE L'OSOSE

# OJO IBERE AWE IMALE.

Eko— Awon igbimo Musulumi ti ile Nigeria ni nwon pinnu ibere awe ti odun 1961 si ojo Alamisi bi a ba ri osu ni ale ojo Alaruba.
Sugbon a ri osu, akori osu awe nilati bere ni ojo Jimo, 17th Feb, 1961.




## Ijongbon Ile Tiv

Makurdi- Enia meji-le-lo gbon ti won je omo egbe UMBC dapomo Action Group ti nwon fi sun esun tena-bole ni asiko ijoagbon ile Tiv ni nwon ti fi ejo won ranse si Kotu Asa-isi ti Makurdi lati Kotu adajo kekere ti ilu Gboko.

Ninu Kotu kanna, ni nwon ti ju Yoosu Jenyi ti o je omo egbe Kanna si ewon odun meta fun esun wipe o tena-bole Asiwaju egbe N. P. C. ni abule Tsar Awon enia meje miran ti o je omo egbe kanna ni nwon ju s'ewon osu metale-logbon fun enikokan fun irufe ese kanna, nwon si da enia meji sile.

Awon meje na ti bere aye fun arotuuro ejo won, sugbon Kotu ko gba iduro fun won.

## Awon Osise Ile Isura ijoba se eye fun Gomina agba.

Eko— Ni ale ojo Jimo (Friday) ose ti o koja ni awon egbe osise Ile Isura ti ijoba (Treasury Social Club) f ero kan ti o ma nse isiro-owo ta Olola nla Dokita Nnamdi Azikiwe, Gomina Gbogbo-gbo ti ile Nigeria lore nibi ipade agbajo ti awon egbe na fi se eye funu.

Olola nla Gomina Agba, Dokita Azikiwe yi ti sise ni Ile Isura Ijoba nilu Eko ninu odun 1921titi de 1924.

# ELETI--OFE

ANJUWỌN KÒ ṢE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS

28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI-OFE"

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIII. NO. 684. SATURDAY FEB 11, FEB. 17, 1961


## ONI LOJO IDIBO ILU KAMARUN PE

Ọjọ idibo ilu Kamarun ti apa isalẹ ti pe loni nisisiyi, a nireti wipe awọn enia ti bẹrẹ, ibo didi, yio si ti maa lọ bi rẹrẹ.

Awọn enia ilu Kamarun ti apa isalẹ ati ti Ariwa ti awọn mejeji ti nlo pọ pẹlu ilẹ Nigeria fun ọdun gbọrọ, ti ni lati mọ amodaju igbadun ti o nbẹ fun wọn nilẹ Nigeria. Nitorina, laiṣeyemeji, ilẹ Nigeria ni ki nwọn faramọ.

Awọn enia ilẹ Kamarun ti apa isalẹ ati ti Ariwa ko ni imọ tabi oye nipa irufẹ ijọba ti awọn ilẹ Kamarun ti o ti wa pẹlu Faranse tẹlẹ ri, ti o tun wa di ada ijọba wọn ṣe nisisiyi jẹ, nitorina, nwọn ko nilati fẹti si moran-dan-moran-danmbọrọ ikede ti Ọgbẹni Foncha ati Ọgbẹni Ahidjo nṣe, ki nwọn maṣe faramọ Kamarun ti Ọgbẹni Ahidjo. Ọna ati ko wọn lọ sọnu sinu ọfin abamọ ni nwọn nwa fun awọn enia Kamarun apa isalẹ ati ti Ariwa.

Ẹ F'ARAMỌ ILẸ NIGERIA.

## Ile Nigeria Gba'yi O Gbe'ye

ILESHA - Alabojuto ilu, ti ijọba Iwọ-orun, Ọgbẹni Duro Ogundiran, ni o sọ wipe iyi ati eyẹ ti ilẹ Nigeria gba lọdọ awọn ilu okere jẹ ti jiran rere ti ko nṣe onijagidi-jagan, o mba awọn ọlọpa ibilẹ Ilesha sọrọ ni o fi sọrọ yi.

O ṣe awọn ọlọpa ni iranti eru nla ti o wa lori wọn fun itọju ilu ati nigba awọn ọdaran laye ti ilu yio fi ni alafia, o nsọ ki o ye wọn wipe alọsiwaju ilu mbẹ lọwọ wọn gẹgẹbi nwọn ba ti ṣe iṣẹ awọn ni rere si.

Ọgbẹni Ogundiran sọ fun wọn wipe ijọba on nfẹ ki awọn ọlọpa ga dar dara ninu iṣẹ wọn, nitorin, ni o ṣe sile ẹkọ fun wọn nilu Ibadan. O sọ fun wọn wipe iṣẹ wọn pataki ni ki nwọn ni suru ki nwọn ma si ṣe ṣ'egbe ninu iṣẹ wọn lojojumọ pẹlu awọn ara ilu ti nwọn nṣiṣẹ fun u.

## Awe Oko Imale

A fi wosika wa ọsẹ yi ki awọn ọmọ-iya wa, nipa ti Ọlọrun, ẹlẹsin Musulumi, ku ipalẹwa, nipa ti Ọlọrun, ẹlẹsin Musulumi, ku ipalẹmọ ti Awẹ ti ọjọ rẹ sunmọ etilẹ nisisiyi :- Ki Oluwa Olodumare jọwọ, jẹki awẹ na ba wa ni alafia ati aralile pẹlu arisiki owo ti ao fi gba awẹ na.

Gẹgẹbi awẹ na ti jẹ ọranyan fun Musulumi ododo nipa aṣẹ Ọlọrun, o to ki gbogbo musulumi mọ wipe oṣu Ramadan jẹ oṣu ti o ni apọnle pupọ nitoripe ninu oṣu Ramadan na ni Ọlọrun sọ Kurani kalẹ ti o jẹ afini-mọna fun gbogbo enia.

Nitorina, ẹniti awẹ ba ti ba laiye ninu ẹnyin musulumi ododo nilati gba awẹ na, ayafi ẹniti o ba wa ninu ailera tabi ti o ba nrin irin ajo, ni Ọlọrun gba laye lati fi awẹ silẹ ṣugbọn ki o si ṣe adapada awẹ na nigbati o ba to asiko ti aye wa. Eyi fihan wipe Ọlọrun ko fẹ inira fun awa ẹda ọwọ Rẹ.

## ALASE IROHIN IJOBA LO BE ILU GHANA WO

IBADAN - Oloye E.A.A. Fadayiro ti iṣe Alaṣe Irohin ijọba Iwọ-orun, ilẹ Nigeria ,dakun lọ bẹ ilu Ghana wo. Ọga Onirohin ijọba Ọgbẹni A.Y Eke ba lọ.



Oloye Fadayiro yio bẹ ile iṣẹ Irohin ijọba ilẹ Ghana ati ile iṣẹ Ẹrọ Asọromagbesi wo. Nigbati o ba npada bọ wale, yio ya ni Lome ati Kutonu lati bẹ ile iṣẹ Irohin ijọba ati Ẹrọ Asọrọ-magbesi wo ninu awọn ilu mejeji na. Irin abẹwo na yio gba ọsẹ kan.

A lọ a dara, abọ asunwọn o.

# IJOBA FI GARI RANSE SI KONGO

EKO - A gbọ wipe ijọba wa ti fi gari apo mejilelogun ranṣẹ si awọn ọmọ ogun ti o wa nilu Kongo.

Gari na jẹ eyiti nwọn ṣe nile iṣẹ ẹrọ ti o nse gari, ni Oshodi. Ni ọjọ ọsẹ tokọja ni nwọn fi Ọkọ ofurufu ko lọ.






## Ipade Igbimo Afowosowopo Sise Tile Afrika

EKO - Ninu ipade keṣinde -logun ti igbimọ afọwọsọwọpọ ṣiṣẹ ti ilẹ Afrika ti nwọn nṣe nilu Eko ni awọn aṣoju meji ti ọlu ara wọn.

Ọkan ninu awọn igbimọ na ti o jẹ aṣoju ilẹ Guinea Ọgbẹni Michell Collet, ni o sọ wipe ayẹ ti ilẹ Kongo wa ṣe yi ni ẹlẹṣẹ, ati pe ki a jẹki ilu na tọrọ ki a to gba wọn sinu ayọ irufẹ eyi.

Ọgbẹni A. B -Boliko f'esi dahun wipe diẹ ninu awọn aṣoju ilu miran ti o ma ndasi ọrọ ilu Kongo, paapa awọn ara ilu Guinea o sọ wipe bi a ba ri eniti ko fẹ ijọba ti o n ninu awọn igbimọ, a le da ẹnikẹ duro, ati pe Kasavubu ni Olori ilu Kongo, o si ni ẹtọ lati da ẹnikẹni duro nigbakugba, ko si nṣe ẹtọ fun ilu miran lati dasi ọrọ ti o ba jẹ ti ilẹ miran.

O tun sọ fun igbimọ wipe, ilẹ Kongo ni iṣe pupọ nilwaju ti o nfẹ ayẹwo, o si ni ireti pe wọn yio ba nwọn ti si laipẹ.

Nihin ni aṣoju ilẹ Guinea tun fesi rọ, sugbọn Alaga da duro wipe ki a ma ko ọro iṣelu wa sibẹ. O sọ wipe ohun ti o ṣele ni Kongo rekọja ohun ti a le gbe sori atẹ nihin. Ki a maṣe fa mọ.

E Ma Ka

Iwe Irohin

ELETI – OFẸ

LOSOSẸ

O KUN FUN IROHIN

ALADUN

# IJA NLA FE BE SILE NILU KUMBA

KUMBA -- Awọn ẹgbẹ oṣelu meji fẹrẹ gbe ija nla ... ko ara wọn ni Kamarun apa isale awọn ẹgbẹ oselu ti Ọgbẹni John Foncha Olotu Ijọba, (KNDP) ati awọn ẹgbẹ oṣelu ti Dokita E. M. L. Endeley, Aṣiwaju Alatako (CPNC).

Ijọngbọn na fẹ bẹ silẹ nigbati awọn kan fa iwe ikede ti awọn ẹgbẹ keji lẹ kakiri ode ya, ti awọn ọmọ ẹgbẹ ti o ni iwe na ri, ibẹ ni agan ti fẹbẹ.

Ọpẹlọpẹ awọn ọlọpa ti o tete de'bẹ ni ko jẹki ija na di ija nla, awọn aṣiwaju wọn meji ni ọlọpa mu, ṣugbọn nwọn ko sọ orukọ awọn ti nwọn mu na.

A tun gbọ wipe ija pẹpẹpẹ tun ṣelẹ kakiri ṣugbọn ko si eyiti o le ninu awọn ija na.

# ADAJO KOTU IBILE W'EWON

EKO - Oloye E.A. Ṣosanya, Onigbanjo ri, ti o di adajọ Kotu ibi ...ilu Ikẹnne ni Onidajọ Kotu Yaba, ṣa konko ẹwọn ọdun mẹrin mọ lara ni ọjọ Monday ọjọ kẹfa oṣu February, 1961 yi, lori ẹsun ole jija.

Ẹsun ti nwọn fi Ṣosanya sun na ni wipe o ṣe afọwọra owo ọgọrundin-lẹgbeje ponun (£1,300) ti o gba lori ile ti o ta Ọgbẹni Michael Ṣodipẹ ta nigbati o nṣe iṣẹ alaja gbanjo. Ẹsun keji ti nwọn tun fi sun ni wipe o ji owo ẹgbẹfa ponun (£1,200) ti o jẹ ti Ọgbẹni Oyemade.

Nigbati nwọn pe ẹjọ na ni Kotu ni ọjọ Monday awati ni nwọn fi Oloye Ṣosanya ṣe. Adajọ ti paṣẹ wipe ki nwọn lọ ti iwe ipa gbe, ki o to yọ si Kotu nigbati agbajọro rẹ mbẹbẹ fun u lọwọ.

Ṣosanya paapa ti gba wipe on jẹbi ẹsun owo ẹgbẹfa irinwo ponun ti on ji, owo Ọgbẹni Oyemade. Ṣugbọn Ọgbẹni Oyemade ti sọ ni Kotu wipe iya iyawo Ṣosanya ti san [illegible] pada.

Ki adajọ to ṣe idajọ, ẹsun titun miran ti wọn tun ka si Ṣosanya lọrun, ni wipe o ji owo irinwo ponun (£400) ni ilu Warri, owo ti o jẹ ti ijọba. Nwọn yio ṣe ẹjọ rẹ ni ilu Warri ni ọjọ kẹtala oṣu yi.

Nigbati adajọ nṣe idajọ lori ẹsun meji, o sọ wipe bi enia ba ro ... ọdaran yi wo, ... Onigbanjo ati adajọ oluwarẹ ko ni ṣai lodi si iwa ... owo ... de owo rẹ nigbati o wa ni ipo ẹniti a nilati ... gbogbo ... ti Lọya rẹ mbẹ ... gbo'jufo owo ... ti o poora.

Nitorina, ki o lọ ṣẹwọn ọdun mẹrin fun ẹsun akọkọ, ọdun mẹta fun ẹsun keji. Ki gbogbo rẹ jijọ siwọ pọ.

# Awamoto Oniwakuwa Farakorin

ILỌRIN - Awamọto kan ti o njẹ Lasisi Ajayi ti awọn Ọlọpa fi sun ẹsun iwakuwa mọto atipe o nwamọto ti idaduro mọto na ko dara.

Adajọ bu ponun mẹdogun (£15) fun ni sisan si apo ijọba tabi ẹwọn oṣu mẹfa ti ko ba ri owo san

Kotu tun paṣẹ wipe ki nwọn gba iwẹ aṣẹ rẹ ti o fi nwa mọto fun oṣu mẹfa.

# "Jaburata" Tun De Kotu Ibadan

IBADAN - Ninu Kotu Asaisi ti ilu Ibadan ni awọn apẹlẹwọn meji ti de iwaju adajọ Ọgbẹni W. H. Irwin fun ẹsun mẹta ti nwọn si jẹbi ole jija pẹlu ipa. Ẹnikini ni Ṛasaki Akanbi ti adape rẹ njẹ "Jaburata" ati Rasaki Ayinla.

Awọn Ọlọpa fi awọn mejeji sun ẹsun wipe "Jaburata" ati Ayinla ti awọn mejeji nṣe ẹwọn lọwọ nisisiyi ninu ogba ẹwọn tilu Eko, ti lọ da awọn enia l'ọna ti nwọn si lu wọn, nwọn si tun ja wọn lole owo ponun meje ati ṣile mẹta ni ọna Ogbomọsọ si Oko ninu oṣu August 1959.

# IROHIN IDUNNU LATI KONGO, ILU IJONGBON

Leopoldville-- Irohin idunnu ti a ri gbọ lati ilu Kongo ilẹ onijọngbọn ni wipe awọn enia mẹrin ti a ti gbọ pe nwọn ṣọnu ninu ọmọ ogun ilẹ wa nihin, Nigeria,ni gbati ija dawọn pọ pẹlu ọmọ ogun awọn alatilẹhin Lumumba ni awọn mẹta de ninu wọn, nwọn si sọ wipe ẹnikan ti o ku lehin mbẹ l'alafia.

Awọn ọmọ ogun na sọ wipe nigbati ija gbojikan ni awọn farapamọ ni asiko ti ibọn nrọjo lọjọ Jimọ ti ija na ṣelẹ.

A gbọ wipe nwọn ma fi ọkọ ofurufu gbe oku ọmọ ogun ti o ku si ogun ile Kongo pada wale fun ati sin oku rẹ. Ọmọ ogun na ni Lt. Godwin O. Ezeugbana ti ijọ ọmọ ogun karun tilẹ Nigeria.

# OBA OBINRIN GUN ERIN NILE INDIA



ENITI a nwo ti o joko lori gaari golu pẹlu Maharaja (Ọba) ilu Jaipur
lori Erin ti nwọn şe lọşọ daradara yi ni Alaiyeluwa Elizabeth Keji,
Ọba obinrin ilu Oyinbo Gẹsi, ti o gun Erin rin kakiri Opopo ilu Jaipur
nigbati o nlọ sibi apejọ iyẹsi nla ti nwọn şe fun u ni Afin ọba ilu na.
Lehin ni ọkọ ọba gun Erin miran tẹle. Eyi ni ọjọ keji ti ọba obinrin
desi ilẹ India.


M.B.T

(MAGIC BLOOD TONIC)



Iná dé, òkùnkùn paradà. M.B.T dé, òkùnrùn fò lọ. Ẹ̀jẹ̀ dúdú sáré, òyì pòşẹ̀şẹ̀. Aló buburú wọ'gbó, òilèsùn rẹ̀hin-ẹ̀kùn. M.B.T. kògùn-ẹ̀jẹ̀ ti nmú ni jẹun b'ìkàn amú ni yàgbẹ́ bi òkùn, amú ni tọ̀ bi àkère. Abiwẹrẹ fàboyún, ogbẹjẹ fun awọn abiyamọ. Ahọn-dúdú, ẹsẹ-wíwú ati àiyà-jíjá ko si pẹ́rátí nlo o. 4/6d pẹlu 1/6d owó-ọkọ̀.

ARADAN STORES P.O.Box ? EBUTE-METTA.


nwọn ko fi ni jẹ niya fun gbigba iyawo Oji Otiwa orukọ ọlọpa na njẹ Alexander Agweyo, obinrin na njẹ Theresa Otiwa.

Ọkọ iyawo Ọgbẹni Oji Otiwa sọ ni Kotu ibilẹ wipe ọrẹ ni on ati ọlọpa na. Awọn iijọ njẹ awọn si jijọ nmu pọ ni, ninu ile on ni ọpọlọpọ igba.

Nwọn fi riro ẹjọ na siwaju.

## Nwon fi Asoju-ona sun esun ole

Kano — Ọkunrin onişẹ Aşoju-ọna ile işe Ifiweranşẹ Posts and Telegraphs nilu Kano, ti orukọ rẹ njẹ Thamas Ikpen, ni awọn ọlọba fi sun esun ole lori owo ti o le ni ẹgbẹta-din logdọn pọnun (£5, ... 11 ti o poora ninu ile işẹ na.

O sọ wipe on ko jẹbi, Kotu ko gba iduro rẹ Nwọn paşẹ ki o wa ni iti. mọle fun ọjọ mẹrinla ki nwọn to ro ti iduro rẹ wo. wọn riro ẹjọ na si ọjọ kọkan-le-gun oşu March, 1961.

Ọga awọn awọn ọlọpa-inu ti o wa lẹkun Kano ati Katsina sọ wipe bi awọn ba le ri ẹniti yio fi ọna hau ti nwọ fi le ri owo na gba pada, nwọn yio fun ni ẹbun tojọju.

## Olopa Gbayawo Ore Re

ILỌRIN - Ọmọbinrin adelebọ kan ti ọkọ rẹ fi se awati ninu ile wọn. ti o si lọ sọ ni Şọbu awọn Ọlọpa wipe on kori iyawo on fun bi ọjọ mẹta kan ni nwọn pada ri obinrin na ninu ile ọlọpa kan.

O pe ọlọpa na lẹjọ si Kotu Alikali nilu Ilọrin, wipe ki o wa se alaye ti

## Alaga Eto Atunse Kongo De Silu Eko

Ikẹja Ọlọla Ọgbẹni Jaja Wachuku ti işe Alaga igbimọ ti o lọ Silu Kongo fun eto ipari ẹ-ọtẹ ilu na, lati ọdọ ẹgbẹ Majọ obajẹ Agbaiye (U.N) ni o ba ọkọ ofurufu pada de silu Eko ni ọja Tuesday ọsẹ yi lati Leopodville, ilu Kongo.

Ni kete ti o sọ kalẹ lati inu ọkọ ofurufu ni o sọ fun awọn oniwe irohiu wipe on mu irohin nla bọ Şugbọn on ko ni sọ fun ẹnikẹni titi ti on yio fi ba Olori ijọba wa, Alhaji Sir Abubakar, sọ

Ẹniti o tun pada de pẹlu rẹ ninu ọkọ kanna ni Ọga awọn ọmọ ogun Major General N.L. Foster, ti alaşẹ gbogbo awọn ọmọ ogun ilẹ Nigeria.

# KELVINATOR REFRIGERATORS



## The Ideal Choice For the Modern Kitchen



CAPACITY
4.6 cu. ft.
6 cu. ft.
7.7 cu. ft.
9.4 cu. ft.
12.8 cu. ft.
H. P. TERMS AVAILABLE

Distributed by

LEVENTIS TECHNICAL

Available at

LEVENTIS Marina — Iddo — Ibadan — Kano — Port Harcourt — Aba

and leading Department Stores


# AKOSILE TO NIDI

Lati ọwọ John Awojulugbe

JOHN sọ fun wa gbangba pe, ero ọkan rẹ tio fi kọ akọsilẹ tire inu iwe ihinrere nipe, awọn ami wọnyi ti a kọ wọn silẹ nipa pe, ki ẹnyin le gbagbọ pe Jesu Kirisiti ọmọ Ọlọrun ni iṣe, ati pe bi ẹ ba ti le gbagbọ, ẹnyin yio si ma laye ninu oruko rẹ, on kọ tire silẹ lati le sọ fun nyin pe Jesu Kirisiti, ọmọ Ọlọrun ni iṣe, ati pe awọn ti o ba si le gbà a gbọ nipa ki a ka ọrọ rẹ ki wọn le ma wa ninu rẹ titi lai.

John gbe akọsilẹ tire jade lati fi han wa pe on pa-pa igbe-igbe ninu Jesu Kirisiti. Nitori eyi ni on na ṣe fi apẹẹrẹ rẹ silẹ fun wa, lati sọ fun wa pe ohun ti on gba yi, otitọ gan ni ati pe Jesu ti Nasareti, ọmọ Ọlọrun ni iṣe, on ni o ni agbara lati fun ẹnia ni iye gbogbo awọn ti o ba gbagbọ.

Akọsilẹ inu iwe rẹ, on fi ọwọ re sọya pe, ohun ti on nkọ silẹ wonyi ki iṣe ar sọ, ohun ti on ti oju ara on ri ni ti on si ngbọ nigba aiye on n pa bi ba Jesu kakiri. Amọ pe iwe John ti o kọ akọkun ni fun awọn ihin-rere. Nitorina, nigbati aba n a awọn ihin-rere wọnyi, ki a mọ pe ọrọ ti Jesu mu jade ni ẹnu ara rẹ ni awa nka. Ki ṣe pe awa nka iwe itan tabi aroso ẹlomiran.

Iyoku di ọsẹ ti o mbọ

# ORO DIE NIPA ISLAM

Bismillahi Rahamoni Rahim
Lati owo Alfa H. A. Kushoro
12, Sunmọnu Balẹ Court, Ẹpẹtẹdo, Lagos.

Mo ki gbogbo ẹnyin ẹlẹsin Musulumi agbaiye, ati awọn elesin kiristeni agbaiye pẹlu ọrọ mi tosẹ yi jẹ lori ọrọ inu Bibeli ati Kurani. Nitoripe awa Musulumi, a jẹ eniti o gba gbogbo ọrọ inu Kurani gbọ, ti Oluwa sọ fun Anabi Mohammed. Ninu Kurani, Sura 5 aya kẹfa, Ọlọrun sọ pe ave ẹnyin onigbagbo ododo, ti ẹ ba fẹ jọ sin fun Oluwa ṣiwaju, enilati ṣe aluwala, ki ẹ ṣan oju nyin, ati owọ nyin de igunpa, ki ẹ tun fi omi ṣan ori nyin, ki ẹ si tun ṣọn awọn ẹsẹ nyin de kokosẹ. Ni bayi, ni ato ṣe ni ọranyọn, lati wọ ile Oluwa, lati lọ jọsin fun Oluwa Ọlọrun wa.

Ari wipe awa ko ko ofin Ọlọrun yi silẹ, ofihan gbangba pe, awa Musulumi a tẹle tiwa ti Oluwa palẹṣẹ, adupẹ fun Oluwa na.

Awọn Kiristẹni sọ wipe awọn gba iwe Bibeli gbọ daradara. Nitori pe o jẹ iwe ọrọ Ọlọrun. Kiloṣe ti awọn oniwe Bibeli fi ko ofin Ọlọrun silẹ nigbati o jẹ wipe, Oluwa ti sọ fun Anobi wọn, Mose ninu iwe Ekisodu ori 30 ẹse 17 de 22. Oluwa sọ fun Mose pe, Sọ fun awọn ọmọ Isireli, ki nwọn ma wẹ owọ wọn ati esẹ wọn, ṣiwaju ki nwọn to wọ inu Ṣọṣi lọ. Sugbọn awọn ẹlẹsin Kiristẹni ko nse bẹ rara; wọn si wipe awọn gba iwe Bibeli gbọ daradara. Ẹ wa sọ fun wa, ona wo, ni ẹle sọ fun wa wipe, ẹfi gba iwe Ọlọrun yi gbọ? Nigbati o jẹ wipe aṣẹ Oluwa ti o sọ pe ki ẹ ma ṣe, lati irandiran nyin, titi lailai.

Ẹ wa ko ofin Ọlọrun na silẹ lai ko se nise ti Oluwa palaṣẹ fun Mose, ẹ tun lo wo iwe Majẹmu Titun, ti ti iwe Jesu ni Juhanu ori 13 ẹsẹ 3 de 15 ati 17 Ti Jesu tun ko won ki wọn ti ni lati ma ṣe aluwala. Pe on fi apere lele fun yin, sugbọn awọn Kiristẹni, tun ko ohun ti Jesu tun ba wọn sọ ni Johanu silẹ. Ewo gan ni ẹ wa gbagbọ ninu iwe Bibeli? Nitorina, eyi pada, ki ẹ tẹle esin Islam, lati maa se gẹgẹ bi ti wa. Ki ẹ ba le wọ Ijọba Ọlọrun pẹlu daradara.

Moki Ogbẹni Woli Adetoro ati Ogbẹni Awoṣiga pẹlu. Ki wọn le ọrọ wọnyi ye wa. Nitoripe awọn wọnyi ni ẹniti awa Musulumi ri, ti wọn ma nsọ wipe ẹsin wọn lọ tọna, ati Ogbẹni Akande Ogbomoṣọ. Ki wọn jọwọ, lati la yewa, ibiti wọn gbagbọ ninu iwe Ọlọrun atieyiti won ko gbagbo ninu iwe na.

IYOKU DI ỌSẸ TI O MBỌ

Asalam Alaikum

# Ogun Iwosan Ajebidan

Lati Ọwọ Onisegun Eleti - Ọfẹ

## OGUN ARAN AIYA

1. Ewe ta'ba meji, Iyọ obe, ao lọ wọn pọ sinu Ọmọri-igba ao fom si mimu diẹ-diẹ lalaiẹ.
2. Akọ Okuta, Ota inu Iroko, Odidi atare kan, Korofo ẹyindie, ao lọ wọn pọ lila niwọn ṣibi kekere kan lọrolarọ
3. Fesi adie, odidi atare kan, ewe ẹsọ ac jo pọ sinu adi, Ili laro niwọn ṣibi kan.

Printed & Published By The Union Printing and Publishing Company, 25, Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Pasa [illegible]